# ÌLÉPA ÌDÀGBÀSÓKÈ TÓ DÚRÓ ṢINṢIN

NÍ ÈDÈ

# YORÙBÁ

17.18. Ní odún 2020 síse ìranlówó fún awon orílè èdè tò sèsè n dàgbà, àwon erékùsù kéékèèké lati ni àgbékalè awon àkoólè ni ìbámu pelu ojó orí ìran tàbí èyà, ako tabi abo, àlejò tàbí omo onilu,abarapa tabi aláàbò ara/abirùn, ibùgbé ati béè béèlo

17.19. Ní odún 2030 ò pon dandan lati ni ìmò kún ìmò láti le se ìgbélèwòn àseyorí lórí ètò ìdàgbàsókè to lálòpè ti o se ìranlówó àti ìgbéláruge àwon ohun ti won n se ni àwùjo ati láti se ìrànlówó fún ìgbékalè ìlànà ìsètò ilu ni awon ìlú ti o sèsè n dàgbà sókè.



1 ÌṢẸ́ BÙṢẸ

## ÈRÓǸGBÀ KINNI: FIFI ÒPIN SI ÌSÉ NI IBI GBOGBO

1.1. Ní ọdún 2030, òpin yoo dé bá ìsé ati ìyà fún gbogbo èniyàn ni ágbàyè èyí ti o jé pé owó ti won fi jeun ni ojúmó kò pé Dólà kan àbọ̀.

1.2. Ní ọdún 2030, àwon okùnrin, obìnrin ati àwon omodé ti ìyà ńje gégé bí òdíwòn àgbáyé yoo dín kù ní ìpín ìdajì.

1.3. Ṣíṣe àgbékalè òsùwòn ìdáàbòbò ti o péye fun mùtú mùwà ati pàápàá jùlo awon aláìní ati aláìlera ni odún 2030.

1.4. Ṣíṣe arídájú ni odún 2030, pé okùnrin ati obìnrin ní pàtàkì jùlo àwon álaìní ati aláìlera ni ètọ́ ti o dógba sì ètò ọrọ̀ ajé, awon ohun amáyéderùn, ètó si ilé, ilè, ohun àlùmónì, awon ìmò èro ìgbàlódé ati ètò ìsúná ti o fi kan ìròrùn fún èyáwó.

1.5. Àtìléyìn gbódò wà fún àwon aláìní ati àwon aláìlera ní odún 2030. Dídáábò bo wón lówó ìsèlè aburù, àìríná ati ìjàm̀bá àyíká ati agbègbè.

1.a. Ṣíṣe àkójopò awon ohun ìní lati orísi ònà, pàtàkì jùlo ìfowósowópò ìdàgbàsóké lati le pèsè ànító ati ànísékù fún awon orílè èdè ti o sèsè n dàgbà sókè lati gbógun ti ìsé ati òsí ni gbogbo ònà.

1.b. Ṣíṣe ágbékalè ìlànà ti o múná dóko ni orílè èdè, agbègbè ati àgbáńlá ayé lórí gbígbógun ti àìní ati ìyàsótò abo láti gbárùkù ti lílé ìsé ati òsì wo igbó

## ÈRÒŃGBÀ KEJÌ:
## FÍFI ÓPIN SÍ EBI, ÀSEYORÍ LÓRÍ ÌPÈSÈ OÚNJE TO ŃSARA LÓORE, ÀTI ÌGBÉLÁRUGE ISÉ ÀGBÈ TÍ O FESÈ MÚLÈ

2.1. Fífi òpin si ebi ni odún 2030 fún gbogbo ènìyàn ní pàtàkì júlo àwon aláìní ati aláìlera pelu àwon omodé ri oúnje tí ó ń se ara lóre je ni àje to ati aje sékù yípo odún.

2.2. Òpin gbódò dé bá jíje oúnje tí kò se ara lóore ni odún 2030, ki a se àseyorí ni odun 2025 lórí dídékun ìfisòfò awon ògo weere ti ko tii pé odún márùn ún. Kí ètò ti o péye wa lórí oúnje ti o n se ara lóore fún awon òdóbìnrin, aláboyùn, àwon obinrin tó ń tó omo lówó ati awon àgbàlagbà.

2.3. Isé àgbè ati èrè olóko àroje ni láti gbèrú ni ílòpo méjì ní odún 2030 ni Pàtàkì jùlo àwon obìnrin, omo onílè, awon eléran òsìn ati olósìn eja nípa ìpèsè ilè ati awon ohun èlò isé àgbè, idanilekoo, ìpèsè owó, ojà fun àníkún àǹfààní ise àgbè.

2.4. Ní odún 2030, àrídájú gbódò wà fún ìpèsè oúnje ti o fesè múlè sinsin, ètò ise àgbè fún ìpèsè oúnje ni yanturu ti o ni agbára láti kojú ìyípadà ojú ojó, ògbelè/èrùn, omíyalé ati àwon ewu miran ti o le se ìrànwó ati fún ilè ní òrá.

2.5. Ní odún 2020, síse àmúlò oní rúurú èso, ohun ògbìn, eran òsìn níle ati lóko nipase itoju aka fun èso ati ohun ògbin ni orile èdè, agbègbè ati àgbáyé ati jije ànfààní ti o wa láti ara àwon èso àti ohun ògbìn gégé bi o se je ìfenukò ni àgbáyé.



### ÀGBÉKALÈ ÌMÒ ISÉ FÚN ÌDÀGBÀSÓKÈ

17.9 Síse àtìléyìn awon orílé èdè àgbáyé fun áwon orílè èdè to sèsè n gbèrú láti ìlanà lati mú ayé rorùn fún won

### OKO ÒWÒ

17.10 Ìsàgbékalé òfin ati ìlànà ti ko se eléyàmèyà ni ìbámu pèlú àjo àgbáye lati le se òwò lábé WTO lati mu ki ìdàgbàsókè dè ba orò ajé.

17.11 Síse àfikún ìdókò òwò ilé òkèèrè fun àwon orílè èdè to sèsè n dàgbàsókè lati le je ki won ni ìlópo méji ìdókòwò ilè òkèèrè ni odun 2020.

17.12 Ṣíṣe àgbékalè ètò èdínwó owó ibodè sísan lórí àwon ojà ti won kó wo àwon orílè èdè to sèsè n gbèrú ati pe àyè wa fún won láti tà ojà won ni orílè èdè tó wù wón

### ÌLÀNÀ ISÉ

17.13. Ìsàgbékalè ati ìfesèmúlè ìlànà isé ati ètò ìmúlò fún ìdàgbàsókè

17.14. Ìfilólè ìlànà isé to ni ètò fún ìdàgbàsókè ti o fesè múlè sinsin

17.15. Ìbòwò fún ètò ìmúlò ìlànà ise orílè èdè gbogbo ati ìsakóso ti o fesè múlè lati gbógun ti isé ati ìyà ati lati sètò fún ìdàgbàsókè tó lálòpé

17.16. Ìgbéláruje ìbàsepò àjo àgbáyé fun ìdàgbàsókè ti o lálòpé nípa ìbákégbé ati àjolò ìmò ero, ìmò nípa ìsúná owólati gbárùkù ti àwon orílè èdè ti o sèsè n gbèrú ni pàtàkí jùlo

17.17. Ṣíṣe ìwúrí ati ìgbéláruge àjosepò tó dán mónrán láàrín àwon elégbéjegbé ilé isé ìjoba lati le se àmúlò ìrírí ati ànfààní ìbákégbé pò.

## ÉRÒŃGBÀ KETÀDÍNLÓGÚN: ÌRÓLÁGBARA ÌLÀNÀ AMÚSÉSE ÀTI ÌSODÒTUN ÀJOSEPỌ̀ ÀGBÁYÉ FÚN ÌDÀGBÀSÓKÈ TO DÚRÓ SINSIN

**ÈTÒ ÌSÚNÁ**

17.1 Ìsàtìléyìn fún àwon ònà ti owó ti n jáde si àpò ìlú lati je ki gígba owó orí ati àwon owó miran wolé si àpò ìjoba

17.2 Kí àwon orílè èdè ti o ti dàgbàsókè se àtìleyìn gégé bi ìpinu won fún àwon ìlú ti o sèsè n gbèrú ni eyi ti ìdá méje nínú ogoorún yoo wà fún ìrànlówó ni ìgbà ti ìdá méèdógún nínú ogoorún yoo je ìrànlówó fún àwon orílè èdè ti ko dàgbàsókè rárá.

17.3 Ṣíṣe àkójopò owó ni onírúurú ònà lati se ìrànlówó fún àwon orílè èdè to sèsè n gbèrú

17.4 Síse ìrànlówó fún àwon orílè èdè to sèsè n gbèrú lati bó nínú gbèsè nípa ìlànà ati ètò lati san gbèsè padà díèdíè, ìdàríjì ati ìfojú fo gbèsè ati pípàrowà si orílè èdè àgbáyé ti wón je ni gbèsè lati fún won ni sùúrù ati ònà ìròrùn lati san gbèsè.

17.5 Ṣíṣe àgbékalè ònà ìdókoòwò fún àwon orílè èdè to sèsè n dàgbà sókè

**ÌMÒ ÈRO**

17.6 Ṣíṣe ìfesèmúlè ìfowosówópò láàrín àwon èyà lati ni oore òfé si ìmò èro ìgbàlódé ati ogbón àtinúdá ati lati le se àjopín ìmò ni pàtàkì jùlo ni ìlànà ti àjo àgbáyé gbé kalè

17.7 Ìgbéláruge ìdàgbàsókè nípa síse alájopín ìmò èro fún àwon orílè èdè to sèsè n gbèrú gégé won se jo fi enu kò

17.8 Ìsàgbékalè àmù ìmò èro sàyénsì ati ìmò àtinúdá fún àwon orílè èdè to sèsè n dàgbàsókè ni odún 2017 ati ni pàtàkì ìsàgbékalè ìmò èro ayára bi àsá kòmpútà



2.a. Síse àfikún ìdóko òwò nípa ìfowó sowópò àgbáyé, nínú awon ohun àmúsagbára, ìmò ìwádìí lori isé àgbè, ìdàgbàsókè ìmò èro ìgbàlódè, àká ohun ògbìn ati ohun òsìn láti lè se àmúgbòrò isé àgbè ní àwon orílè èdè ti o sèsè n tiraka lati dàgbà sókè.

2.b. Ṣíṣe àtúnse ati dídékun ìpàálà ati ìdíwó ni ojà ògbìn àgbáyé nípa yiyo èkúnwó ìrànlówó lórí ojà kíkó lo si òkè òkun gégé bí ìlànà ìdàgbà sókè Dola.

2.c. Ṣíṣe àgbékalè awon ìlànà lati mú ki ojà oúnje fesè múlè sinsin nípa pípèsè àlàyé ni èkúnréré lórí kátà kárà, ni pàtàkì jùlo bí oúnje ti se pò si ni ìpamó lati dékun rira oúnje ní òwón gógó.

## ÈRÒŃGBÀ KETA: ÌPÈSÈ ÌGBÉ-AYÉ ÀLÀÁFÍA ÀTI ÌGBÉ-AYÉ ÌRÒRÙN FÚN GBOGBO ÈNÌYÀN.

3.1. Ní odún 2030, àwon obìnrin ti o n kú ni àkókò tí wón n bímo gbódò dín kù sí ààdórin nínú egbèrún lónà ogóòrún omo ti won bi sáyé.

3.2. Ní odún 2030, fi òpin si ikú àìtójó fún àwon omo àsèsè bí títí kan àwon omo tí kò tíì pé odún márùn ún; ki gbogbo orílè-èdè si se akitiyan lati se ìdínkù ikú omo-ìkókó síbii ìdá-méjilá nínú ogórùn omo egbèrún tí a bí lááyè; kí ikú láàrín omo ti ojó-orí won kò tó odún márùn si dínkù si bíi ìdá-méèdógbòn nínú ogórùn ún laarin egbèrún omo tí a bí s'áyé.

3.3. Ní odún 2030, òpin gbódò dé sí àjàkálè àrùn, àrùn tí kò gbóògùn, ikó fée, àìsàn ibà, ati lati gbógun ti àìsàn jèdòjèdò, àìsán ti won n kó nípasè omi ati àwon àìsán mìírán tí ó lè ran ènìyàn.

3.4. Ní odún 2030, àdínkù nípa ìdá kan nínú méta ikú àìtójó àwon omodé nípasè àìsàn tí kò lè ran ènìyàn ni a gbódò dènà, ki a si se ìtójú nipa ìgbèláruge ati ìpolongo àrùn opolo.

3.5. Ìfèsemúlè fun ìdènà ati ìtójú àsìlò oògùn olóró ati àmupara otí líle.

3.6. Ní odún 2020, ìfarapa ati ikú ti o n wáyé nípasè ìjàmbá ojú pópó ni àgbáyé ti gbódò dínkù ní ìlópo méjì

3.7. Ní odún 2030 a gbódò sètò bi gbogbo àgbáyé yoo se ni ètó si èkó nípa ìbálòpò ati ìfètò si omo bíbí ati síse ètò ìlera ìbísí si inú ìlànà àti àgbékalè ètò orílè èdè.

3.8. Àseyorí gbódò wa lórí ètò ìlera fún gbogbo gbo nípa ànfààní si kòseé mà-ní ètò ìwòsàn ti o péye, ti o múnádóko ti owó re ko ga ni lára ni pàtàkì jùlo abéré àjesára.

3.9. Ìdínkù ti o gbòòròò gbódò ba ikú ati àìsàn ti o n jéyo nípasè kémíkà olóró, ìdòtí inú omi ati ti inu aféfé ni odún 2030.

3.a. Ṣíṣe àtìléyìn ìmúse ìlànà àjo àgbáyé fún ìlera lórí àdéhùn ìsàkóso tábà/sìgá bi o ti ye ni gbogbo orílè èdè.

3.b. Àtìléyìn fún ìwádìí ati ìpèsè abéré àjesára ati oògùn fún àwon àìsàn to le ran ènìyàn ti o maa n je ìdààmú fun awon orílè èdè ti o sèsè n gbèrú, ìpèsè àwon oògùn kò-seé mànì ati abéré àjesára ni òwó ti ko ga ni lára gégé bí ìlànà ati ìfenukò 'Dóhà' ti o fi eto awon orílè èdè ti o sèsè gbèrú múlè si ìwòsàn fún gbogbo ènìyàn.

3.c. Ṣíṣe àfikún owó ìsúná, ìlera, àti gbígba àwon òsìsé, ati ìdánilékòó àwon onísé ètò ilera ni àwon orílè èdè to sèsè n gòkè agba ni pàtàkì àwon erékùsù kéréje kéréje.



16.3. Ṣíṣe ìgbéláruge òfin ati ìlànà òsèlú ni orílè èdè àti ni gbogbo àgbáyé àti ìpèsè ìdájó ododo fún gbogbo ènìyàn.

16.4. Ní odún 2030, a gbódò gbógun ti ìwà àjebánu ati kíkó ohun ìjà olóró wòlú lai gba àse, ki akitiyan wa lati gba owó ìlú padà lówó àwon ajegúdú jerá ati lati dènà gbogbo ìwà òdaràn.

16.5. Gbígbógun ti ìwà àjebánu ati rìbá gbígbà ni gbogbo ònà.

16.6. Ìsàgbékalè awon ilé isé ati ilé ìwé ti o kun ojú òsùwòn tíkò si ni kónú kóho nínú ni gbogbo ibi.

16.7. Kíkó àkóyawó nínú ìsàkóso ati gbígba àmòràn lati òdò gbogbo eni ti o kópa nínú ìdàgbàsókè agbègbè àti àyíká.

16.8. Fífún àwon orílè èdè to sèsè n gbèrú láyè lati kópa ati lati lénu nínú ètò òsèlú àgbáyé.

16.9. Ìpèsè ònà ìdánimò lábé òfin fún gbogbo ènìyàn ati gbogbo omo ti won sèsè bi.

16.10. Ìpèsè ìròyìn lórí ìsèlè ìlú gbódò wa fún ara lati mo ati lati dáàbò bo òmìnira ará ìlú ni ìlànà ati ètò òfin àgbáyé.

16a. Ìrólágbára àwon ìlé isé pèlú ìfowósowópò lati òdò àjo àgbáyé lati se ìrànwó fún àwon orílè èdè to sese n gbèrú láti dènà ìwà agbésùmòmí ati ìwà òdaràn.

16b. Ìgbéláruge ati ìfesèmúlè òfin ati ìlànà ti ko se ojúsajú fún ìdàgbòsókè to fesè múlè sinsin.

15.7. Ìgbésè akin pon dandan lati gbé lati dékun kíkó àwon òdòdó ati ògbìn tíkò wópò jáde lo si agbègbè miran lai gba àse ati wíwá ojútùú si títà ati rírà awon eranko ti won fi òfin dè.

15.8. Ní odun 2020, àgbékalè ètò ati ìlànà lati dékun ati lati se àdínkù ìjeyo awon àjèjì eranko ni awon igbó ati omi òkun ati lati se ìsàkóso ti o lóòrin lati pa wón run.

15.9. Ní odún 2020, ìgbékalè ètò lórí àwon nnkan to je ìbátan elémìí gbódò jeyo ninu ìlànà ìsàkóso ni ìpínlè ati orílè èdè, ìgbésè ìdàgbàsókè ati lílé ìsé wògbé ati ìsúná.

15.a. Şíşe kóríyá ati ípèsè owó ìnání gbogbo ònà lati se àtìléyìn lórí ìtójú awon eranko abèmí.

15.b. Şíşe ìgbékalè/ìpèsè owó lati gbogbo orísun lati se àgbédìde ati àkéso àwon igbó ati lati se kóríyá fún àwon orílè èdè to sese n dàgbà sókè lati le se ìtójú ati ìpamó àwon igbó won.

15.c. Kí gbogbo àgbáyé pawópò lati gbogun ti kiko ati sisode eranko ti won n dáàbo bò to lòdì si òfin ati lati se ìrànlówó fún àwon olùgbé ìgbèríko lati le ri ònà oúnje òòjó won.

16 ÀLÁFÍÀ, ÌDÁJÓ ÒDODO ÀTI ÀGBÉKALÈ ÀWON ILÉ IŞÉ

## ÈRÒǸGBÀ KERÌNDÍNLÓGÚN: ÌGBÉKALÈ ÀWÙJO ÀLÀÁFÍA FÚN ÌDÀGBÀ-SÓKÈ AYÉRAYÈ, ÌPÈSÈ ÌDÁJÓ ÒDODO FÚN MÙTÚMÙWÀ ATI ÌDÁSÍLÈ ILÉ-ÈKÓ TI O PÈSÈ FÚN ALÁÀBO-ARA TI O SI MÚNÀDÓKO NI GBOGBO ÌPÈLÈ ILÉ-ISÉ.

16.1. Fífi òpin si gbogbo ìwà jàgídí-jàgan ati ikú òjijì ni gbogbo ibi.

16.2. Fífi òpin si ìfiyà jeni, ìfowó olá gba ni lójú, ìmúnisìn ati ìmúniserú àti gbogbo ìwà ipá sí àwon omodé.



3.d. Rírò àwon orílè èdè ni agbára ni pàtàkì jùlo àwon orílè èdè to sèsè n dàgbàsókè lati le tètè se àkíyèsí ati lati se àdínkù ewu ìlera ni àgbáyé.

4 ÈTÒ ÈKÓ TÓ MÚNÁDÓKO

## ÈRÒǸGBÀ KERIN: SÍSE ÀGBÉKALÈ ÈTÒ-ÈKÓ TI O KÚN TI O SI PÉ'YE ATI SÍSE AGBÁTERÙ ÀNFÀÀNÍ ÈKÓ TÍTÍ LÁÉ FUN MÙTÚMÙWÀ.

4.1. Àrídájú gbódò wa ni odún 2030 pe gbogbo àwon omobìnrin ati omokùnrin ni ó je ànfàànì èkó ofe ti o yè kooro ni ilé ìwé alákòbérè de ilé ìwé girama pèlú èrí fún àkó yege.

4.2. Ní odún 2030, àrídájú gbódò wà pé gbogbo omobìnrin ati omokùnrin gbódò ni ètó si ìdàgbàsókè ati ìtójú titi kan ètò jéléósinmi eyi ti yòó se ìgbáradì won fun ilé èkó alákòbéèré.

4.3. Ní odún 2030, àǹfàní ti o dógba gbódò wa fún gbogbo obìnrin ati okùnrin lati ko isé owó ti o ye kooro, lati lo ile iwe gíga de Fásítì ni owó póókú.

4.4. Ní odún 2030, oye àwon òdó ati àgbà ti o ni isé owó ati ìmò àtinúdá ti o dájú, ti yoo ri isé ti o dára se, gbódò gbèrú sókè dáradára

4.5. Ní odún 2030, òpin gbódò de si àìdógba èkó láàrín okùnrin ati obìnrin, ìpèsè gbogbo ìpele èkó ati isé kíkó fún àwon aláàbò ara ati àwon ti o ku díè kaa to fun.

4.6. Ní odún 2030, a gbódò ri dájù pe àwon àgbàlagbà lòkùnrin ati lobìnrin ati gbogbo òdó, gbódò mòo ko, ki won mòó kà, ki won si le se ìsirò.

4.7. Ní odún 2030, àrídájú gbódò wà pe gbogbo akékòó gbódò ni ìmò kìkún lati se ìgbélarúge ìlépa ìdàgbàsókè ti o fi ìdí múlè sinsin lati ipasè ètó fún omo ènìyàn, àìsì eléyàmèyà láàrín okùnrin ati obìnrin ìgbéláruge àsà ati ìse, ìpolongo àlàáfíà ati ìfé láàrín orílè èdè àgbáyé àti ìfé si orísirísi èyà pèlú àsà àti ìse won.

4.a. Kíko ati síse àgbékalè ètò èkó ni pàtàkì fún omodé, aláàbò ara se kókó ni ìbámu pèlú àlàáfíà ati ààbò agbègbé.

4.b. Ní odún 2020 àfikún gbódò ba oye èkó òfé ti awon orílè èdè ti o sèsè n gbèrú n je ànfààní ni pàtàkì jùlo àwon erékùsù kéékèèké ati àwon orílè èdè Afrika, fún ìforúko sílè fún ile èkó gíga, ilé èkó ìkósé ati ilé èkó ìmò èro ni àwon orílè èdè ti o ti gbèrú.

4.c. Ní odún 2030, àfikún gbódò bá ìpèsè olùkóakósémosé nípasè ètò àfowósowópò àgbáyé lati se ìdánilékò fún àwon olùkó ni àwon orílè èdè ti o sèsè n gbèrú ati àwon òlukó lati àwon erékùsù kéékèèké.

ÈRÒǸGBÀ KARÙN ÚN: SISE ÀSEYORÍ LÓRÍ ÌBÁDÓGBA OKÙNRIN ÀTI OBÌNRIN, ÀTI ÌRÓLÁGBÁRA ÀWON OBINRÌN ÀTI ÒDÓMOBÌRIN

5.1 Fífi òpin si gbogbo ònà ìyàsótò ati ìkórìrì àwon obìnrin àti òdómobìrin ní àwùjo.

5.2 Fífi òpin si gbogbo ìwà ipá àti ìfinijìyà fún àwon obìnrin àti òdómobìnrin ni àwùjo àti ni igun ilé kòòkan ni pàtàkì jùlo fífi obinrin ati odomobirin se owo eru at owo nabi /sina ni ilu okeere àti àwon ònà ìfiyà je ènìyà mìíràn.



ÈRÒǸGBÀ KARÙNDÍNLÓGÚN: ÌDÁÀBÒBÒ, ÌSÀGBÉNDE ÀTI ÌGBÉLÁRUGE, ÌSÀMÚLÒ ÀWON ERANKO ÀTI EWÉKO, SÍSE ÌTÓJÚ ÀWON IGBÓ, DÍDÉKUN SÍSO ILÈ DI ASÁLÈ, DÍDÉKUN ILÈ BÍBÀJÉ ÀTI ÀWON ERANKO ATI EWÉKO.

15.1. Ní odún 2020, àrídájú gbódò wa fun ìtójú ati àtúnse àwon ilè, inú ilè, òkè, òkun ati etíkun nì ibámu pèlú etò ati ìlànà ti àjo àgbáyé fi enu kò sí.

15.2. Ní odún 2020, ìpolongo ati ìmúse ìsàkóso àwon onírúrú igbó, dídékun igbó píparun, àtúnse ati ìmúpadàsípò awon igbó ati igi igbínbìn lati da igbó pada gbódò jé ìdá mewa ninu ogóòrún bi o ti le wu ki o kéré mo.

15.3. Ní odún 2020, a gbódò gbógun ti igbó píparun ki a si se àtúnse ati àtúntò awon igbó ati ilè ti won ti bàjé nipa ògbelè, omíyalé ati awon isé ati akitiyan awon ènìyàn.

15.4. 2030 àrídájú gbódò wà fun ìpamó ati ìdáabobò awon òkè lati le je ki won se ànfààní ti o se pàtàkí fún ìdàgbòsókè ati ìmúgbòrò agbègbè.

15.5. Gbígbé ìgbésè pàtàkí lati dékun igbó píparun ati ìpàdánù ti o wáyé nipa ìpínsíyéle yèle ki ìgbésè akin si wa ní odun 2020 lati dá ààbò bo awon eranko inú ìgbé ni pàtàkí jùlo awon ti won ti fee parun tán.

15.6. Ṣíṣe ìpíndógba àwon ànfààní ti o wáyé lati ara awon eranko ati irúgbìn ti o ni ìbátan ìfijogún.

14.5. Ní odún 2020, ìpamó gbódò wa fún ìdá méwá nínú ogorun àwon etíkun ni ìbámu pelu àgbéye ati ìtónisóna ìmò sáyénsì.

14.6. Ní odún 2020, ìdíwó ati ìdènà gbódò wa fún àwon ònà ìpeja eyi ti o n fa ìjàmbá ati àkótán eja nínú ibú. Fífi òpin si àwon ònà ti ko ba òfin mu ti won n gbà kó eja nínú òkun pèlú fifi àwon orílè èdè to sese n gbèrú sókàn ati àwon erékùsù ni ìbámu pèlú àdéhùn àjo àgbáyé lórí òwò síse.

14.7. Ní odún 2030, síse àfikún ànfàànì okoòwò si àwon orílè èdè ati erékùsù ti o n dàgbàsókè nípa àwon orò ajé ti o jeyo láti etíkun nípasè isé eja pípa ati ìrin afé.

14.a. Ṣíṣe àfikún ìmò ìjinlè sáyénsì ati ise ìwádìí nipa etíkun pelu ìbámu ati ìlànà àwon egbé ‘Oceanographic Commission’ lati se àtúnse si àwon etíkun gbogbo eyi ti o le mu ìdàgbàsókè ati ìlosíwájú ba àwon orílè èdè ati erékùsù ti o sèsè n dàgbàsókè.

14.b. Ìpèsè ati ìtónisónà fún àwon apeja olóko òwò kékeré si àwon ojà ati ibùdó ti won yoo ti ri ojà won tà.

14.c. Ṣíṣe ìdáàbò ati ìpamó àwon òkun ati etíkun pèlú èrò ati ohun àlùmónì gege bi o se wà ni àkoólè inu òfin UNCLOS ti o pèsè ìlànà èto ti o ba òfin mu lòrì lílò àwon etíkun gege bi o se wa ni ese kejìdínlógojo iwe.

**“The future we want” - “Ojó òla ti afé”**



5.3 Fífí opìn si gbogbo ìwà ìpalára bíi fífí omobìnrin fún oko laítíì bàlágà ati kíkolà/dídábé fún omobìnrin.

5.4 Mímo rírì ati pàtàkì isé ilé ati isé ìrànlówó òfé nípasè òfin amáyéderùn, isé àwùjo ati ojúse enìkòòkan ninu ebí gégé bi o se ye.

5.5 Àrídájú gbódò wa fún ìkópa àwon obínrin àti àǹfààní dídógba lati kópa nínú òsèlú ati ipò àse ni gbogbo ònà ati ni gbogbo ibi.

5.6 Ṣíṣe àrídájú ètò ìwòsàn nípa ìbísí ati ìbálòpò gégé bi àbájáde ìfenukò ìpàdè ICPD ati àgbékalè àpérò Beijing.

5a. Àtúnse àwon àgbékalè ti yoo fún obínrin ni ètó lati je orò ati lati ni ìpín nínú ogún ilè ati àwon ohun ìní ati àlùmónì gege bi o ti wà nínú òfin àgbáyé

5b. Ṣíṣe ìgbélàruge ìmò èro ni pàtàkí jùlo ìmò èro ìbánisòrò ìgbàlódé lati fi polongo ìrólágbára àwon obínrin.

5c. Ṣíṣe àmúlò ìlànà ètò ti o dúró sinsin ti o sìbá ofin mú lati polongo ìbádógba àwon obínrin pèlú okùnrin ati ìrólágbára àwon obínrin ati òdómobínrin ni gbogbo ònà ati ni gbogbo ibi

## ÈRÒNGBÀ KEFÀ: SÍSE ÌPÈSÈ OMI ATI ÌMÓTÓTÓ FÚN GBOGBO ÈNÌYÀN.

6.1 Ní odún 2030 àseyorí gbódò wà nípa ìpèsè omi mímu ti o mó ní owó póóku fún gbogbo ènìyàn.

6.2 Ní odún 2030 ìpèsè ìmótótó ti o péye fún gbogbo ènìyàn nípa fífi òpin sí síse gá/ìgbònsè si àyíká ati agbègbè ni pàtàkì jùlo pípèsè ohun èlò kòséémàní fún àwon obínrin, omodébínrin ati àwon tí kò dá pé/aláàbò ara.

6.3 Ní odún 2030 àtúnse gbódò dé ba omi nípa ìdínkù aféfé bìbàjé, dídáwó dúró lórí dída ìdòtí ati àwon kémíkà olórò sínù omi ati sise ìtójú omi kí won tó mu ú.

6.4 Ní odún 2030, ìpese omi ti o dára ti o si mo gbódò wàni yanturu fún gbogbo ènìyàn lati kojú òwón omi ati se ìrànlówò fún àwon ti ìyà omi n je.

6.5 Ní odún 2030, ìpèsè omi fún gbogo ènìyàn ati ni ibi gbogbo pèlú ìfowósowópò gbogbo àgbáyé gégé bi o ti ye.

6.6 Ààbò ti o péye gbódò wà ní odún 2020 fún àwon nnkan elémìí ninu omi ati àwon ìbátan ati ogbègbè bii àwon òkè, igbó, odò ati adágún omi.

6a Ní odún 2030 àmúgbòrò gbódò ba ìfowósowópò láwùjo àgbáyé láti gbárùkù ti àwon orílè èdè to sèsè n dàgbàsókè nípa ìpèsè omi ati ìmótótó ni pàtàkì jùlo ànìto ati ànísékù omi .

6b Àtìléyìn ati ìròlágbára fún àwon ará ìlú lati kópa nínú àtúnse ati àmúdára omi ati ìmótótó àgbègbè

## ÈRÒǸGBÀ KEJE: SÍSE ÌPÈSÈ INÁ MÒNÀMÓNÁ TI KII SÉ'JÚ TI O LÁLÒPÉ NI OWÓ PÓÓKÚ

7.1 Ìpèsè iná mònàmóná ti ìgbàlódé ti ó ní àlòpé ni owó póókú ni odún 2030.

7.2 Ní odún 2030 àfikún yoo ba iná ti o se lálòpé ní àgbáyé.

7.3 Ní odún 2030, àfikún ni ìlópo méjì yoo de ba agbára iná mònàmóná.



13.a. Ṣíṣe àmúse èjé ti àwon orílè èdè ti o ti ni ìdàgbàsókè jé níwájú àjo àgbáyé to n ri si òrò ìyípadà ojú ojó lati maa se ìrànwó owó to je bílíònù lónà ogórùn dólà lódoodún lati fi kojú ewu ati ìjàmbá ti àwon orílè èdè to sèsè n dàgbà sókè n kojú látàrí ojú ojo yiyipada ati sise agbedide igi ati eweko gbingbin lati ran ojú ojó lówó.

13.b. Ìgbéláruge ètò èro fún ìgbáradì ati ìsàkóso ìyípadà ojú ojó ni àwon erékùsù ati ìgbèríko ni ìfojúsùn julo fún àwon obínrin, òdó ati àwon ìlú kéréje kéréje.

## ÈRÒǸGBÀ KERÌNLÁ: SÍSE ÌTÓJÚ ATI LILO OHUN ALUMONI INU OMI OKUN ÀTI ÒSÀ FÚN ÌDÀGBÀSÓKÈ TI O NÍ IKÌMÍ.

14.1. Ní odún 2025, ìdíwó ati ìdènà gbódò wà fún ìdòtí ati ìbaféféjé omi òkun ni pàtàkì julo àwon pàntí ti o n wò inú òkun lati orí ilè.

14.2. Ní odún 2020, ìsàkóso ati ìdáàbò bo àwon òkun ati etíkun lati dènà ìkolù aburú nipa sise ìpadàbòsípò ati ìsojí lati se àkóso etíkun ti o ni òrá ti o si n pawó wolé.

14.3. Síse àdínkùn ati wíwá ojútù si omi òkun ati ìdòtí aféfé to n se àkóbá fún nípasè ìmò ìjìnlè sáyénsì ni gbogbo ònà.

14.4. Ní odún 2020, ìlànà ati ètò gbódò wa fún eja pípa, eyi ti yoo fi òpin si kíkó gbogbo eja kúrò nínú òkun ni ònà àìtó eyi ti o n se àkóbá fún isé eja pípa nípa lílo ìmò ati ètò sáyénsì ìgbàlódè lati se ìdápadà àwon òkun wa si ipò ìwúlò won.

12.8. Ní odún 2030, àrídájú gbódò wa pe gbogbo ènìyàn ni o ni òye ati ìmò nípa ìgbé ayé àlàáfià ni àyíká ti ewéko ati eranko àbáláyé wà.

12.a. Ṣíṣe àtìléyín fún àwon orílè èdè to sèsè n dàgbàsókè lati se àmúgbòrò ìmò sáyénsì ati ìmò èro ti yoo fún won ni ètò ìlànà ti o dúró sinsin ninú ìpèsè ati lílo àwon nnkan ti won n se.

12.b. Ṣíṣe àgbékalè ati àmúlò àwon irin isé ti yoo se àmójútó ìrìn àjò afé nípasè eyi ti yoo pèsè isé ati ìgbéláruge àsà ati isé àwon ènìyàn.

12.c. Ṣíṣe àtúntò ati àmúkúrò àwon èkúnwó epo eyi ti o n se ìjàmbá ati sísòfò orò ajé ati síse àtúntò ati àtúngbékalè owó orí eyi to n se jàmbá fún àwon orílè èdè ti o n gbèrú lówó ati lati dáàbò bo àwon alaìní ati àwon agbègbè ti irú ètò béè se àkóbá fún.

## ÈRÒǸGBÀ KETÀLÁ: GBÍGBÉ ÌGBÉSÈ ATI ÀMÓJÚTÓ LÁTI DÉKUN ÌYÍPADÀ OJÚ-OJÓ ÀTI EWU TI O RÒ MÓO.

13.1. Ṣíṣe àgbékalè ìlànà ati ètò ìmúpadàbò sípò léyìn ìjàmbá pàjáwìrì ti o nsisé pèlú ìyípadà ojú ojó.

13.2. Ṣíṣe àfikún ètò ati ìlànà ojú ojo yíyípadà sínú ìlànà òfin ati ètò ìmúlò orílè èdè.

13.3. Ṣíṣe ìpolongo ati ìtanijí fún àwon ènìyàn lori bi a se le koju ewu ti o wa nínú ìyípadà ojú ojó pèlú ìmúrasílè ati ìsàkíyèsí àwon ìyípadà agbègbè.



7a Ní odún 2030 ìfowósowópò pèlú àjo àgbáyé yoo gbèrú si ìpèsè ati ìwádí ti o múnádóko lori ìpèsè iná oba ti o lálòpé ni pàtàkì jùlo ìsodòtun ati àtúnlò iná oba ati ìtèsíwájú nínú ìdókòwò nínú ìpèsè iná oba.

7b Ní odún 2030 àmúgbòòró yoo de ba ònàèro ati amàyèderùn lati se ìpèsè iná ìgbàlódé ti o ni àlòpé fun gbogbo awon orílè ti o sese n dàgbà sókè, àwon erékùsù kéékèèké ati ìpínlè gege bi àkosílè ìrànlówó se wa fun won.

## ÉRÓǸGBÁ KEJO: ÌGBÉLÁRUGE ÀTI ÌSÀTÌLÉYÌN FÚN GBÍGBE-RÚ ORÒ AJÉ ÀTI ÌPÈSÈ ISE TI O DÁRA FÚN GBOGBO ÈNÌYÀN.

8.1 Ìfesèmúlè okò òwò ati orò ajé ni ìbámu pèlú ìlànà àgbàyé ni pàtàkì jùlo ìdá meje ninu ogóorún ni odún ti o wa fun orílè èdè ti o gbèyìn jùlo nínú ìdàgbàsókè.

8.2 Àse yege ti o ga jùlo nínú àbájáde òrò òye nípa ìdóko òwò lorisirisi ònà, gbígbé láruge ìmò èrò lati dojúko síse isé takuntakun.

8.3 Ṣíṣe ìpolongo ati ìgbéláruge àwon ìlànà ati ètò fún ìdàgbàsókè ati ìpèsè isé owó, sise ìmò àtinúdá ati lati se kóríyá fún àwon olóko òwò kéékèèké nípa ìrànlówó owó.

8.4 Ìtèsíwájí nínú odún 2030 fún ànító ati ànísékù orò ajé ati àtinúdá síse lopo àwon ohun èlò lati gba ètò orò ajé lówó iná ajoreyin ni ibamu pelu ilana eto olodun mewaa lori ise sise ati ìgbèrú si orò ajé nínú eyi ti àwon orílè èdè to sèsè n dàgbà sókè ti gbódò je olórí.

8.5 Ní odún 2030 àseyorí kíkún gbódò wà lórí ìpèsè ise ti o dára fún gbogbo obínrin, okúnrin, òdó, àwon ti o ni ìpèníjá èyà ara ti owó ti won yoo gba maa ni ìbámu pelu isé ti won se.

8.6 Ní odún 2020, ye àwon òdó ti ko ni isé lówó, tí kò sí ní ilé ìwé tí kò sí ní enu èkósé gbódò dín kù.

8.7 Gígbé ìgbésè ti o nípon gbódò wáyé lati dékun ati lati fi òpin si gbogbo ònà ti won n gba lo awon omodé gégé bi erú, fifi omodé se isé ti o ni agbára ati wi pe ni odun 2025 òpin gbódò dé si ìfomo serú ati eyi ti o nii se pèlú fifi awon omodé ja ogun.

8.8 Ààbò gbódò wà fún ètó omonìyàn nipa isé sise ati lati sètò agbègbè tíkò ni ewu fun àwon òsìsé ni pàtàkì julo awon àtòhúnrìnwá tabi àjòjì ni pàtàkì julo awon obìnrin ati awon ti o n se isé ti o ni ewu púpò.

8.9 Ní odún 2030, àgbékalè eto ati ìlànà gbódò wáyé ti yoo se ìgbéláruge ètò ìgbafé nípasè eyi ti isé yoo wa ni yanturu fun awon èniyàn ti yo si se àfihàn ati ìgbéláruge àsà ati ìse pelu isé ìsèn báye awon èniyàn.

8.10 Ṣíṣe àtìléyìn fun awon ìdókòòwò lati le se àtìléyìn ati àmúgbòròile ìfowópamó ìbílè, ilé okòòwò màdàmílófò ati eto ìròrùn lati ri owó se isé.

8.a Ṣíṣe àfikún ìranlówó òwò sise fun awon orílè èdé ti o sese n dàgbàsókè ni Pàtàki jùlo awon orílè èdè ti o rèyìn julo nípasè ètò ati ìlànà ìrànlówó oko òwò fun awon orile ede ti o sese n gbèrú.

8.b Ní odún 2020, àgbékalè ati ìlànà ti o gbórín gbódò wa lati pèsè ise fun awon òdó eyi ti yoo wa ni ìbámu pelu ilana àjo òsìsé àgbáyé.



## ÈRÒǸGBÀ KEJÌLÁ:
## SÍSE ÀRÍDÁJÚ ÌLÀNÀ TI O FESÈMÚLÈ SINSIN FÚN ÌPÈSÈ ATI RÍRA ÀWON OHUN ÈLÒ.

12.1. Ṣíṣe àgbékalè ìlànà ètò olódún mewa lori ìpèsè ati rírà ohun èlò eyi ti àwon orílè èdè ti o ti dàgbàsókè se agbáterù re nigba ti ìlera ati ìdàgbàsókè àwon orílè èdè yoku se pàtàkì

12.2. Ní odún 2030, àseyorí yoo wáyé ni lílò ati ìsàkóso àwon ohun èlò àdáyébá.

12.3. Ní odún 2030, ìdínkù ti o lóòrìn yoo wáyé lórí fifi oúnje sòfò lati òdò àwon aláràje ati aláràtúntà ati ìfoúnje sòfò to n wáyé ni àkókò ti won n pèsè ati ti won n kórè won.

12.4. Ní odún 2020, àseyorí gbódò wa lori ìtójú ati ìsàkóso àyíká kúrò lówó ewu kémíkà olóró ní ìlànà ati ètò ti àjo àgbáyé gbé kalè lati se ìdínkú bi àwon kémíkà olóró se n wo inú omi, aféfé ati ilè lati din ìjàmbá ti ose ti wo n se ìlera omo èniyàn.

12.5. Òsùnwòn ègbin ti an se yoo dínkù ni odún 2030 nípasè didena ègbin, ati ìlòtúnlò won.

12.6. Ṣíṣe ìwúrí fun àwon ilé ise ni pàtàkì jùlo ilé isé ti o ni èka káàkiri orílè èdè, àgbáyé lati se àmúlò àsà alálòpé si ètò àkoólè ati ìròyìn won.

12.7. Ìgbéláruge ònà láti gba nnkan eyi ti o ni àlòpé ni ìbámu pèlú ìlànà ati ètò àjo àgbáyé.

11.3. Ní odún 2030, ìgbékalè ètó ìsògbédìgboro ti o fesè múlè sinsin ati ìlànà ìtèlúdó fun awon èniyàn gbodo wa káàkiri oríle èdè.

11.4. Sísapá akitiyan lati dáàbò bo, awon ìsèsè ati àsà abínibí.

11.5. Ní odun 2030, ìlànà ati ìgbésè lati se àdínkù iye awon ti o kú, ati awon ti wàhálà ba nípasè àjálù omíyalé pelu ìlàkàkà lati dáàbò bo àwon aláìní ati aláìlera.

11.6. Àkíyèsí pàtàkì gbódò wa fún ìsèlè àyíká ati àgbègbè ni awon ilu nla ni pataki aféfé ti o nfé, kólè kódòtí ati ìlànà ìtójú ègbin ati àyíká.

11.7. Nínú odun 2030, ìpèsè ogbà oko tútù ti o ni àbò ti o péye fun awon obìnrin, omodé, arúgbó ni pàtàkì awon aláàbò ara.

11.a. Àtìléyìn gbódò wà fún ìbásepò awon ìgbèríko, ìlétò ati àwon ìlú nla nípasè orò ajé, ìbágbé àwujo ati agbègbè.

11.b. Ní odún 2020, àfikún yoo wa fun awon ìlú nlá, ati ìlétò ti o n kópa nínú ìlànà ati ètò fùn ìgbáradì ìfaradà ojú ojó to n yí padà ati ìjàmbá àti ìsètò ìdàgbàsókè ni ìbámu pèlú ìlànà 'Sendai' lori bi ase le din ìjànbá ati ewu kú ni gbogbo ònà.

11.c. Ṣíṣe àtìleyìn fun awon orílè èdèè to rèyìn ninu ìdàgbàsókè nípa ìranlówó owó ati ìmò èro lati kó ile ti yoo ni àlòpé nipa lilo awon ohun èlò ti won se ni àyíká won.



## 9 ÈRÒǸGBÀ KESAN: SÍSE ÀGBÉKALÈ ÀWON NǸKAN KÒSEÉMÀNÍ ALÁLÒPE ATI ÌGBÉGA ILÉ-ISÉ ŃLÁ ATI ISÉ-ÀTINÚDÁ

9.1 Ìpèsè ohun kòseémàní ti o ni àlòpe, ti o see fi okàn tè, ninueyi ti ohun kòseémàní laarin orile ede meji lati se àtìléyin oko òwò ati orò ajé, ni pàtàkì ìfòkànbale àti ìgbé ayé ìròrùn awon èniyàn.

9.2 Síse àgbékale àti ìdókòòwò ti o kun ti ósì fesèmúle sinsin, ati ni odún 2030 síse ìgbé dìde ìpín isé síse gégé bi ìbámu àgbékalè GDP.

9.3 Ìpèsè owó yíyá fún awon olóko òwó kéékèèké ati onílé isé kéréje ni pàtàkì jùlo ni awon orílè èdè ti idàgbàsókè won kòtíì gbèrú nipa sísan èlé ti ko ga ni lara lórí èyáwó ati ìpèsè oníbàrá fún ojà won.

9.4 Ni òdun 2030, ìgbésókè awon ohun kòseé mánì lati je ki won ni àlòpé pelu àmúgbòrò orò ajé ti o jáde nípasè ìmò èro ati àyíká ti o mó tònítóní eyi ti orílè èdè kòòkan gbódò se gege bi agbára won ti tó.

9.5 Ṣíṣe ìgbélárugbe ìwádìí ìmò ìjìnlè, àtúnse àwon èró ìgbàlódé ni pàtàkì jùlo àwon orílè èdè ti o sèsè n dàgbàsókè ni odún 2030 ati ṣíṣe ìwúrí fún ogbón àtinúdá ti yoo je ki àwon òsìsé pò si.

9.a Ṣíṣe agbáterù àwon nnkan kòséémànì ni àwon orílè èdè tio sèsè n dàgbàsókè nípasè ìpèsè owó, ati ìmò èro fún àwon orílè-èdè Afrika ti o sese n dàgbàsókè ati àwon erékùsù kéékèèké.

9.b Ṣíṣe àtìléyìn fún àwon orílè èdè to sese n gbèrú nípa àwon nnkan èlò ile Isé ìwádìí ati isé àtinúdá ati ètò ìlànà òsèlú ti o mú ayé rorùn fun ati da oko òwò sile ati àtúnse àwon isé won.

9.c Síse agbáterù ìpèsè ìròyìn ati èro to mu ìbásòrò rorùn ati lati tiraka lati pèsè èro ayelújára fún àwon èniyàn ni àwon orílè èdè to sèsè n dàgbà sókè ni odún 2020.

10 ÌFÒPIN SÍ ÀÌDÓGBA

## ÈRÒNGBÀ KEWÀÁ: ÀDÍNKÙ ÀÌDÓGBA NÍNÚ ORÍLÈ ÈDÈ ÀTI LÁÀRÍN ORÍLÈ EDE.

10.1. Nínú odún 2030,Ìlosíwájú gbódò wà ninu owó óyà awon òsìsé ni ídà ogóji ninu ogórùn eyi ti o gbódò ju ti gbogbo gbò lo.

10.2. Ìrólágbára ati àtìléyin gbódò wà nípa orò ajé, òsèlú ati ìdàgbàsókè gbgogbo èniyàn ni odún 2030 lái se ojúsàjú nipa ojó orí, okunrin tabi obìnrin, àwò, èyà, ìlú, èsin tàbí àwon nnkan mìíràn.

10.3. Àrídájú ìdógba ànfaàní nípasè sise déède ni gbogbo ònà ni pàtàkí julo òfin síse ati àgbékalè ìlànà ati eto ti o wan i ìdógba fun gbogbo èniyàn.

10.4. Ṣíse àgbákelè ìlànà ìsètò ìnáwó owó òyà ati ètò àbò eyi ti àtúnse yoo maa bá ni òòrè kóòrè.

10.5. Ṣíse àtúnse si ìlànà òfin ati síse àbojútó ètò ìsúnà àgbáyé ati làti se àmúlò irú ìlànà béè.

10.6. Ṣíse ògbùfò ati asojú fún àwon orílè èdè to n gbìyànjú lati gbèrú nínú ìgbìmò àgbáyé lori ètò orò ajè ati ìsúná ki won ba le ni ìsàkóso ti o dájú ti o si fi ese múlè sinsin.



10.7. Ṣíṣe àgbékalè ònà ìròrùn ti ko ni ewu eyi ti àwon èniyàn le maa gbà lati rìn ìrín àjò lati orìlè èdè kan si òmíràn nípa ìlànà ati òfin tí ó fesèmúlè.

10.a. Ṣíṣe àmúlò òfin ati ìlànà pàtàkì lati maa ba àwon orílè èdè ti o n sèsè gbèrú lo ni ìbámu pèlú àlàkalè àjo agbaye lórí orò ajé.

10.b. Fífi àyè gba ìrànlówó owó ati ìdásílè oko òwò lati gbárùkù ti awon orílè èdè, ìpínlè, ni Afrika ti o sèsè n gbìyànjú láti gbèrú àti awon erékùsù ti ko tii ni ìdàgbàsókè to ni ìbámu pèlú ètò ati ìlànà won.

10.c. Nínú odún 2030, àdínkù gbódò de ba owò ti awon àlejò n san fun ìgbelu ni ìdá méta nínú ogorun ki awon ìloro ti ibùdó ti owó sísan ti ju ìkó marun nínú ogorun di tìtí pa.

11 ÌFÌDÍMÚLÈ ÀWỌN ÌLÚ ÀTI ÌLETÒ

## ÈRÒNGBÀ KOKÀNLÁ: ÌPÈSÈ ÀÀBO TO DÁJU ATI ÌGBÉ-AYÉ ÌRÒRÙN FÚN ÀWON ÌLÚ NLÀ ATI ÌLETÒ.

11.1. Ìpèsè ilé ti o dára, ti o ni àbó ti o péye ni owó póókú gbódò wan ni àrowótó gbogbo mùtúmùwà pelu awon ohun amáyé derùn ni odún 2030.

11.2. Ní odún 2030, ìpèsè eto ìrìnnà tí kò ní ewu, tí kò wón ti o sín í àlòpé gbódò wa fun gbogbo èniyàn, síse àtúnse àwon ojúònà wa nípa fífè won lati le fi àyè gba awon alábò ara lókùnrin, lóbìnrin, lómodé ati àgbà.

United Nations
Information Centre
(UNIC), Lagos

17, Alfred Rewane (Formerly Kingsway) Road Ikoyi,
P.O. Box 1068, Lagos, Nigeria.

Tel: (01) 4630915  E-mail: lagos@unic.org

Website: www.lagos.sites.unicnetwork.org

facebook: United Nations Information Centre (UNIC), Lagos.
Twitter: @UNICLagos


designed & printed by: Media Culture Mkting Comm. Ltd.
08033911598, 07088889792

1 ÌṢẸ́ BÙṢE

2 EBÍ DÓPIN

3 ÌWÒSÀN TÓ PÉYE ÀTI ÌGBÉ AYÉ ÌRỌ̀RÙN

4 ÈTÒ ẸKỌ́ TÓ MÚNÁDÓKO

5 ÌBÁDỌ́GBA ÈTỌ́ ỌKÙNRIN ÀTI OBÌRIN

6 ÌPÈSÈ OMI TÓ MỌ́ ÀTI ÌMỌ́TÓTÓ ÀYÍKÁ

7 ÌPÈSÈ INÁ OBA NÍ OWÓ PÓKÚ

8 ÌDÀGBÀSÓKÈ ỌRỌ̀ AJÉ ÀTI ÌPÈSÈ IṢẸ́

9 OKO ÒWÒ, ÌMỌ̀ ÀTINÚDÁ ÀTI OHUN AMÁYÉDẸRÙN

# ÌLÉPA ÌDÀGBÀSÓKÈ TÓ DÚRÓ ṢINṢIN

NÍ ÈDÈ

# YORÙBÁ

10 ÌFÒPIN SÍ ÀÌDỌ́GBA

11 ÌFIDÍMÚLẸ̀ ÀWỌN ÌLÚ ÀTI ÌLETÒ

12 ÌBÁDỌ́GBA ÌPÉSÉ ÀTI LÍLO ÀWỌN OHUN ÈLÒ

13 AKITIYAN LÓRÍ OJÚ ỌJỌ́

14 ÀWỌN OHUN ẸLẸ́MĨ NÍ ABẸ́ OMI

15 ÀWỌN OHUN TÍ Ó Ń GBÉ LÓRÍ ILẸ̀

16 ÀLÁFÍÀ, ÌDÁJỌ́ ÒDODO ÀTI ÀGBÉKALẸ̀ ÀWỌN ILÉ IṢẸ́

17 ÌFỌWỌ́SOWỌ́PỌ̀ FÚN ÀṢEYỌRÍ ÀWỌN ÌLÉPA ÌDÀGBÀSÓKÈ

SUSTAINABLE DEVELOPMENT GOALS